# ALABAṢIṢẸ PỌ̀ PẸLU ỌLỌRUN

**Iṣe Awọn Apọsteli 18:24-28; 1 Kọrinti 1:11, 12; 3:4-9**

**ẸKỌ 337 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Bẹ̃li awa, ti a jẹ́ pipọ, a jẹ́ ara kan ninu Kristi, ati olukuluku ẹ̀ya ara ọmọnikeji rẹ̀" (Romu 12:5).**

## A fi Apollo hàn

Ni akoko ti Paulu wà ni Jerusalẹmu, Apollo, ojiṣẹ Ọlọrun lati Alẹksandria, ti Egipti bẹ awọn ijọ ti o wà ni Efesu wo. Oun kò i ti di ọmọlẹyin Jesu; iwaasu rẹ̀ lakọkọ kò dabi iwaasu Paulu, Peteru, Barnaba, ati awọn Onigbagbọ́ miiran ti o ti n waasu ni Efesu. Ju ni Apollo i ṣe o si mọ́ Iwe Mimọ́ daradara; ṣugbọn oun ki i waasu bi ti awọn Farisi, tabi awọn olusin gẹgẹ bi igbekalẹ awon Ju ti wọn fi dan dan lé e pe Ofin nikan ni a gbọdọ waasu. Apollo ti gbọ́ iwaasu Johannu Baptisti, o si gba ohun ti o gbọ́ lẹnu rẹ̀ gbọ́.

Johannu ti waasu pe: "Ẹ ronupiwada; nitori ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ̀" (Matteu 3:2). Apollo ti kẹkọọ pé Messia n bọ̀ wá; lai si aniani, o ti kà lati inu asọtẹlẹ Isaiah pe Johannu Baptisti yoo wá gẹgẹ bi "ohùn ẹniti nkigbe ni ijù, ẹ tún ọ̀na Oluwa ṣe, ṣe opópo titọ́ ni aginjù fun Ọlọrun wa." Nigba ti Apollo gbọ́ iwaasu Johannu, o gbà á gbọ́.

O ṣeeṣe ki Apollo wà ni Egipti ni akoko ti Jesu n ṣe iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀, ki o má tilẹ gbọ́ rara pe Jesu ti dé gẹgẹ bi Messia, ati pe a ti kan An mọ agbelebu, O si ti jinde. Iroyin ki i tete tàn kaakiri ni ọjọ wọnni gẹgẹ bi o ti ri lọjọ oni. Awọn Ju ti i ṣe ọta Kristi kò tilẹ fẹ́ ki ihin naa tàn kaakiri rara.

## A kọ́ Apollo Dajudaju

Akuila ati Priskilla, awọn ẹni ti o ti n bá Paulu ṣiṣẹ pọ̀, ti o si wà ni Efesu gbadun iwaasu Apollo. O jẹ "ẹniti o gboná li ọkàn," ti "o nfi ãyan nsọ̀rọ, o si nkọ́ni ni nkan ti Oluwa." O n waasu ohun gbogbo ti o mọ̀, kò si sọ ohun ti o lodi si ohun ti Paulu ti waasu rẹ̀. Ṣugbọn oun kò mọ̀ pe ohun nla ti oun n sọ wi pe yoo ṣẹlẹ lai pẹ ti ṣẹlẹ sẹyin. Jesu ti wá, O ti kú, O si ti jinde kuro ninu okú.

Akuila ati Priskilla mu un lọ si ile wọn, wọn si bẹrẹ si sọ "ọ̀na Ọlọrun fun u dajudaju." Lai si aniani, wọn sọ ohun ti Paulu ti waasu fun un, ani wi pe Kristi ti kú lori igi agbelebu gẹgẹ bi etutu fun ẹ̀ṣẹ, O si jinde pẹlu, lati fi hàn pe Ọmọ Ọlọrun ni I ṣe. Ibikibi ti Paulu ba lọ, o n waasu Olugbala ti O ti jinde ti O si lagbara lati fọ́ itẹgun ẹ̀ṣẹ ati lati gba gbogbo awọn ti o ba ke pe E pẹlu igbagbọ́ ati ironupiwada là.

## A Gba Itan naa gbọ́

Bi o tilẹ jẹ pe oniwaasu pataki ni Apollo i ṣe, boya ẹni ti ọ̀pọlọpọ eniyan n tọ̀ lẹyin ni oun i ṣe pẹlu, tayọtayọ ni o fi tẹti lelẹ lati gbọ́ itàn iyanu ti Akuila ati Priskilla n sọ. Apàgọ́ ni wọn, ṣugbọn o mọ̀ pe wọn ni ọ̀rọ iye, o si gba a gbọ́. Ẹni ti n fẹ otitọ tọkàntọkàn kò fẹ mọ̀ ẹni ti o waasu Jesu fun un. Ọdọmọde ti o ni igbala le sọ itàn yii pẹlu irú idaniloju kan naa ti agbalagba le fi sọ ọ. Iwọ ha ranti ẹrubinrin nì ti o sọ fun Naamani adẹtẹ nipa wolii ti ó wà ni Israẹli. Ọmọde kekere ni oun i ṣe, o si tun jẹ́ ẹrú pẹlu, ṣugbọn o mọ agbára Ọlọrun Israẹli, ẹ̀ru kò si ba a lati sọ nipa Rẹ̀.

## Apollo rin Irin-ajo

Lẹyin ti a ti ṣe ọ̀pọlọpọ ipade ni Efesu, Apollo lọ si Akaia lati waasu, awọn Onigbagbọ́ kọwe pe Apollo n waasu otitọ kan naa ti Paulu ti fi kọ́ wọn. Ọlọrun ni o fi iṣẹ naa le Paulu lọwọ.

Bawo ni o ti ùn tó pe Apollo lo ẹ̀bun ọ̀rọ sisọ ti o ni fun ogo Ọlọrun! O mọ Iwe Mimọ́ pẹlu, nitori eyi, o le fi yé awọn eniyan dajudaju pe Jesu ni i ṣe Kristi ni tootọ́. Ẹmi Mimọ́ mu awọn ẹ̀kọ́ ti o ti kọ́ tẹlẹ wá si iranti rẹ̀ lati fi imuṣẹ Ọrọ Ọlọrun hàn fun un.

## Ariyanjiyan

Apollo waasu ni Kọrinti, ilu miiran nibi ti Paulu Apọsteli paapaa gbé ti waasu. Awọn eniyan gbà ọ̀rọ rẹ̀ gbọ wọn si fẹran rẹ̀ nitori otitọ ti o n sọ. Ṣugbọn rogbodiyan bẹ́ silẹ̀ nitori pe awọn kan fẹ́ Paulu ju Apollo, ijọ si pin si meji.

Paulu kọwe si ijọ Kọrinti, o si jẹ ki wọ́n mọ̀ pé wọn n ṣe ohun ti kò tọ́. Ihin Jesu ni wọn ni lati feti si ki wọn si fi sọkàn, dipo ki wọn gbe oniwaasu ka iwaju wọn.

Paulu kò wa ojurere fun ara rẹ̀. Jesu ni o n gbega nigba gbogbo; o tilẹ n fẹ ki oun di ẹni ifibu ki awọn Ju sa ti ri igbalà. O sọ fun awọn ara Kọrinti pe: "Emi Paulu tikarami fi inu tutù ati ìwa pẹlẹ Kristi bẹ̀ nyin, emi ẹni irẹlẹ loju nyin nigbati mo wà larin nyin, ṣugbọn nigbati emi kò si, mo di ẹni igboiya si nyin. Ṣugbọn emi bẹ̀ nyin pe ki o máṣe nigbati mo wà larin nyin ni mo fi igboiya han" (2 Kọrinti 10:1, 2). O n sọrọ pẹlu "igboiya," nigba ti Apollo jẹ́ olohun-iyọ, ṣugbọn o ni agbára Ọlọrun, Ọlọrun si lo iṣẹ-iranṣẹ rẹ̀ fun igbalà ọ̀pọ ọkàn.

Kò si iwe miiran laye yii ti o tá awọn iwe ti Paulu apọsteli kọ yọ. Ọlọrun lo o nitori ti o rẹ ara rẹ̀ silẹ ati pe o fi ogo fun Ọlọrun fun ohun gbogbo ti o ṣẹlẹ ninu iṣẹ-iranṣẹ rẹ̀.

Paulu bere pe, "Kini Apollo ha jẹ? kini Paulu si jẹ? bikoṣe awọn iranṣẹ nipasẹ ẹniti ẹnyin ti gbagbọ́, ati olukuluku gẹgẹ bi Oluwa ti fun" (1 Kọrinti 3:5). Agbọrọsọ lasan ni wọn jẹ́ fun Ẹmi Mimọ́. Wọn sọ Ọrọ ti Ọlọrun fi rán wọn. Ẹnikẹni ki yoo ri igbala nipasẹ iwaasu Paulu tabi Apollo bi Ẹmi Ọlọrun kò ba fi òye ẹ̀ṣẹ yé wọn. "Ẹmi ni isọni di ãye; ara kò ni ère kan" (Johannu 6:63).

### Igbala Nipasẹ Orukọ Jesu

"Kò si orukọ miran labẹ ọrun ti a fifunni ninu enia, nipa eyiti a le fi gbà wa là" (Iṣe Awọn Apọsteli 4:12). Gbogbo iwaasu awọn Onigbagbọ́ duro lori otitọ yii pe, Ọlọrun ni Kristi i ṣe. Kò ni si agbára ninu orukọ yii yatọ si ti ẹnikẹni ninu awọn wolii tabi oniwaasu pataki miiran bi Jesu ki i bá ṣe Ọmọ Ọlọrun. Paulu wi pe, "Bi Kristi kò ba si jinde, njẹ asan ni iwãsu wa" (1 Kọrinti 15:14). Eyi ni pé, bi Jesu ki i bá ṣe Ọmọ Ọlọrun, kò ṣanfaani lati maa waasu igbagbọ́ ninu Kristi. Ṣugbọn Kristi jinde kuro ninu okú ninu ara ologo, ati pe a o sọ ara gbogbo awọn Onigbagbọ́ tootọ ti o kú ninu igbagbọ́ di aaye lati "bá ara ogo rẹ̀ mu."

Paulu sọ fun awọn ara Romu pe Jesu jẹ ẹniti a pinnu Rẹ̀ "lati jẹ pẹlu agbara Ọmọ Ọlọrun, gẹgẹ bi Ẹmi iwa mimọ́, nipa ajinde kuro ninu okú" (Romu 1:4). O fi hàn pe Ọlọrun paapaa ni Oun i ṣe nipa fifi Ẹmi Rẹ̀ lelẹ, lẹyin naa O si tún gbà á pada – ohun ti wolii, alufaa tabi ọba aye yii kan kò le ṣe.

Paulu, Apollo ati Peteru (ẹniti a pe ni Kefa nihin yii) waasu ẹ̀kọ́ ipilẹṣẹ Ihinrere, tayọtayọ ni awọn eniyan si fi n gbọ́ ọ̀rọ wọn gẹgẹ bi wọn ti n waasu ọ̀rọ naa, olukuluku ni ọ̀na tirẹ. Gbogbo iwaasu wọn ni lati gbé Ijọ ró. Wọn n fẹ ran awọn eniyan lọwọ ki wọn le wà ni imurasilẹ lati pade Jesu, wọn kò si waasu lati gba ogo fun ara wọn.

### Iṣẹ Wà fun Gbogbo Wa

Afo wà fun olukuluku iranṣẹ Oluwa lati di, kò si eredi ti ẹnikan yoo fi jowu ẹnikeji. (Lai si aniani, bi owu-jijẹ ba wà rara, Ẹmi Ọlọrun ti fi ẹni naa silẹ.) Opin kan naa ni gbogbo awọn iranṣẹ Ọlọrun n lepa. Ẹnikan n funrugbin Ihinrere, ẹlomiran si wá, o n bu omi rìn irugbin naa nipa ìwaasu rẹ̀. Bi ọjọ ti n gori ọjọ, èpo le ti hù saarin irugbin naa, o si yẹ ki a faa tu. O ṣeeṣe ki o jẹ pe iwaasu alufaa miiran ni yoo fi ibi ti "èpo" ti o yẹ ki a fa tu naa gbe wà ninu igbesi-ayé oluwarẹ̀ hàn. Niwọn-igbati alufaa naa ba n waasu gbogbo Ọrọ Ọlọrun, ti o si n gbé igbesi-ayé ohun ti o n waasu, lai yọ kuro ninu rẹ̀, ti kò si gbòjẹ̀gẹ́ nipa otitọ, iranṣẹ Oluwa ni ẹni naa i ṣe, o si yẹ ki a gbọ́ tirẹ̀ ki a si fara mọ́ iṣẹ-iranṣẹ rẹ̀, ẹnikẹni ti o wù ki o jẹ.

## AWỌN IBEERE

1 Ta ni Apollo?

2 Nibo ni Apollo ti wá?

3 Bawo ni o ṣe waasu ni Efesu?

4 Ki ni Akuila ati Priskilla sọ fun Apollo?

5 Ki ni ede-aiyedè ti o ṣẹlẹ ni Kọrinti?

6 Ki ni Paulu sọ ninu iwe rẹ̀ si awọn ara Kọrinti nipa ara rẹ̀ ati iṣẹ-iranṣẹ Apollo?

7 Ki ni kokó iwaasu Paulu ati Apollo?